OWE
Ọwọ Baba ni ẹ nwo,
ẹ ko wo ẹsẹ baba.

# Irohin Yoruba

VOL. IX No. 466 MONDAY APRIL 5, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja
nyin sinu iwe
Irohin Yoruba

# Obafemi Awolowo Lo Be Ifo Wo

IFỌ.—Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ ketadinlogbọn oṣu yi ni Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Action Group ati Alakoso Ijọba Iwọ-Orun Nigeria lọ bẹ ilu Ifọ wo.

Iyawo rẹ ati awọn ẹmẹwa diẹ si tẹlẹe lọ, ki nwọn to wọ ilu ni awọn ọdẹ ti yan mẹwa lọ ninu wọn lati lọ pade rẹ, lati ibẹ ni nwọn si ti bẹrẹ si yin ibọn ṣeyẹ funrun titi nwọn fi wọ'lu, lati ibẹ na ni awọn enia ti to ati awọn aṣoju igbimọ ilu Ifọ titi wọ ilu, awọn ọmọ ile-iwe pẹlu Ẹgbẹ "Boy Scouts" si to s'ọtun, s'osi ọna ti nwọn nṣe ayẹsi wọn.

Ni deede agogo mẹwa abọ ni Ọgbẹni Awolọwọ ati awọn ẹmẹwa rẹ ba awọn Igbimọ Ilu Ifọ na ṣe ipade pataki, Ọgbẹni Hanlock Ajẹlẹ-kekere (District Office) si wa ṣe akiyesi ipade igbimọ na.

Ọgbẹni Popoọla Cole, Aṣoju Igbimọ si fi ọrọ apọnle ki Alakoso Ijọba Iwọ-orun na ku-abọ, ninu awọn inkan ti o fi si iwaju Ọlọla na pe o yẹ fun ilu Ifọ ni Ile Ipamọ-owo [Treasury] Ile Ifi-iwe Ranṣẹ (Post Office) Omi-Ẹrọ ati ọna daradara fun anfani awọn ara ilu na. O si tun bẹ ẹ Ọlọla na pe ki o ba awọn ṣe ki owo-afikun owo-ori [Capitation Tax] le dinku si pọnun meji o din ṣile meji (£1:18:0d), nitori bi owo-ori na ti wa nisisiyi inira gbà a ni fun awọn lati san.

Ọlọla na si dupẹ pupọ lọwọ awọn Igbimọ Ilu Ifọ na fun ilọsiwaju ti nwọn ni, o si sọ fun wọn wipe ti on ba pada de Ibadan gbogbo ohun ti nwọn nfẹ ni on o fi si iwaju awọn Igbimọ Aṣoju, o si tẹnumọ fun wọn lati ma a ṣe daradara pẹlu Ijọba, ati nipa didinku afikun owo-ori on a si ti si i de aye pe ki o fi dinku si pọnun kan ṣile mejila tabi pọnun kan abọ.

Ọlọla na si tun ṣe alaye anfani ẹkọ ọfẹ ti gbogbo awọn ọmọde yio ni ati pe ti ẹkọ ọfẹ na ba bẹrẹ Ijọba yio ṣe agbara lati mu aṣọ le-iwe ati iwe ti nwọn o ma fi ṣe iṣẹ ẹkọ wa pupọ ti rira awọn inkan wọnyi ko fi ni ijẹ inira fun awọn obi awọn ọmọ Ile-iwe na.



Aworan Oke yi ni ti Ọgbẹni ati Iyaafin Ọbafẹmi Awolọwọ nigbati nwọn wọ inu Ifọ. Awọn Ẹgbẹ "Boy Scouts" ni o nu papa wọn soke l'ọtun l'osi fun ayẹsi ẹni ọla na ati Iyawo rẹ

## Awon Omo Awe S'eye Fun Alufa Ajao

EKO—Ni deede agogo marun irọlẹ ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ ketadinlogbọn osu ti o kọja yi [27-3-54] ni awọn Ẹgbẹ Ọmọ Awẹ "Awe Improvement Union" ti Ẹka Eko ṣe anya ati aṣe apẹjẹ pataki fun Alufa Kekere [Deacon] A. A. Ajao M. Th; ni 1, Dabara Street Lagos fun oye Diakoni ti a fi jẹ.

Alufa Kekere (Deacon) O. A. Ọkẹ ni o fi adura pataki si ipade na. Nwọn si ya fọto pẹlu Deacon A. A. Ajao na. Ọgbẹni S. O. Ogunmyi ni o fi alaga han. Alaga na si ni Alufa Ijọ Baptist Kini l'Eko, Dokita J. T. Ayọrinde D. D. Alaga na si fi ọrọ alaga si ipade na.

Ọgbẹni J. O. Akanji-Smart ni o sọ ọrọ apọnle Alufa Ajao na, o sọ ọrọ iwuri pupọ nipa rẹ bi o ti ṣe jẹ pe ki iṣẹ ajeji enia si on nitoripe ọran on pẹlu Alufa Kekere na dabi igbati a ba sọ pe ile on orun ti ṣe pe. Nipa bẹẹ o'nun ti on njẹri si nipa iwa rere rẹ jẹ otitọ ti o daju. Awọn Ẹgbẹ na si ta a jọrẹ ẹbun ti o jọju lati ọwọ Omidan Boyin Adeoye.

Deacon A. A. Ajao si I [illegible] ti o gbamuse si ọrọ

Wo oju ewe keji

## Gomina-Kekere Si Ile Iwosan Si Badagry

BADAGRY—Ni aipẹ yi ni Ọlọla Hugo Marshall ti iṣe Gomina-Kekere Ijọba Iwọ-Orun Nigeria lọ si Ile Iwosan (Government Hospital) titun kan si Ilu Badagry, owo ti o pitu Ile Iwosan na jẹ ọkẹ-meji pọnun (£40,000).

Gomina-Kekere na gba awọn ara Badagry ni iyanju pe ki nwọn ṣe daradara pẹlu Ile Iwosan yi, ki nwọn ma fi da agunla bi nwọn ti ṣe pẹlu eyiti nwọn ti kọkọ kọ si ibẹ ni inkan adọta ọdun sẹhin nisisiyi ki ile iwosan na to parẹ lasiko ogun ajakaiye kini (1914-1918).

Ọgbẹni S. O. Ighodaro, Alamojuto iṣẹ Lera Iwọ-orun Nigeria si sọ fun wọn wipe o si ku Agbegbe mẹta ti ko ti ni ile iwosan, nitorina eyiti a si si adugbo yi ẹ fọju ṣe ki Ijọba le ni isinmi lati ma a kọ iyoku, ẹ tun rina, ẹ maṣe de ẹniti o ba nṣe aisan mọle tabi ẹ maṣe jẹki a di igbati aisan ba di oju iku tan ni ẹ o to gbe e wa si ile iwosan.

O si tun ba awọn oniṣẹ ibẹ sọrọ pe ki nwọn fọju iṣe wọn ki awọn enia ma ṣe ri ọran abuku tabi iwọsi kan sọ si wọn lara.

Ki Gomina kekere na to ja okun ti a ta si oju ọna ile iwosan na, Eniọwọ Bisọpu A. W. Howell (Assistant Bishop of Lagos) gba adura. Lemọmu-Agba ilu ibẹ Alfa Gatari Tijani si tun ṣe adura ni ọna ti Musulumi. Awọn ti o tun si ilẹkun ile iwosan na lẹhin Gomina-kekere ni Ọlọla Ighodaro, Iyaafin Marshall, Iyaafin E. D. Akran ati Dokita T. H. K. Montgomery [Director of Medical Service, Western Region], Dokita A. E. Ikomi ti Dokita ti a fi ile iwosan titun na si abẹ-itọju rẹ.

## NWON GUN GAMBARI KAN L'OBE PA

EKO—Ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ ketadinlogbọn oṣu ti o kọja yi ni a ri oku Hausa kan ti a npe ni Mallam Bulingwa eni ọdun medogbọn ti ori simẹnti ti ẹgbẹ sọbu Kora kan ni Ereko ti o na gbalaja, oju ẹgbẹ jinjin kan si wa ni igbaiya rẹ [Eyiti a tọkasi lati oku na yi], awọn kadi ti nwọn fi aṣere wa ni ẹgbẹ Hausa na. Awọn Ọlọpa'tie si ti ṣe iwadi iku rẹ sọdọ awọn Hausa ti nwọn sun si Mọsalaṣi ti ko jinna sibẹ, Hausa na ku si, sugbọn nwọn ko da awọn Hausa na duro.

Bi ya ọkan ninu awọn Hausa ti nwọn jumọ nfi kadi ta tẹtẹ pọ si i o pa a nigbati o jẹ wọn ti ọkan wọn si gbona s'ọda. Bẹni ira inkan bayi yẹ ni ọjọ Rù ti iṣe ọjọ Kewa oṣu keji ọdun yi nigbati a ri oku Gbadamọsi Ọlọrun-ngọla ti o [illegible] sọbu S. C. O. A. kan ni adugbo ni Moloney Bridge Street l'Eko ti nwọn si tọ sibẹ na. Awọn ọeja mẹwa ni awọn Ọlọpa mu lori ọran iku Gbadamọsi na ti nwọn nba ṣe ẹjọ lọwọlọwọ yi.

GET
REDIFFUSION
AND HEAR
WHAT GOES ON
AT HOME
AND ABROAD

